# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 559 THURSDAY MARCH 19, 1964 (2D)


## Elewon Kan Ku Si Ogba-Ewon

IKOYI:— Idaamu nla ba gbogbo awọn alamojuto ogba ẹwọn ati gbogbo awọn ẹlẹwọn nigbati ẹlẹwọn kan, Ọgbẹni Ọlatunji Ayinde, ti o nṣe ẹwọn oṣu kan ooṣẹ aṣekara ṣubulule ti o si ku lojiji ninu ogba ẹwọn ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi.

Oniwe irohin wa Ejongboro, fi ye wa wipe, Ọdaran na, Ọlatunji Ayinde lọ ba ẹnikan ja o ṣe oluwarẹ leṣe, o si tun da ogbẹ si oluwarẹ lara.

Nigbati nwọn mu ọdaran na lọ si Ile-ẹjọ kekere Ikeja, niwaju adajọ Agba Ile ẹjọ na fun esun pe o ja larin ode gbangba, o si da oju ogbẹ si ẹnikeji rẹ lara ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu keji ọdun yi ni Ikẹja, ọdaran na fi ẹnu ara rẹ rojọ o si gba wipe on jẹbi ẹsun na, ni adajọ ba ṣe idajọ pe ki ọdaran na lọ si ẹwọn oṣu kan oniṣẹ-aṣekara.

Lati ọjọ na ni ọdaran na si wa ni ogba ẹwọn, ṣugbọn nigbati o di ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi, ti o ku ọjọ meje ti ẹlẹwọn na yio jade ni o ba ku.

Irohin awọn ọlọpa fi ye wa wipe ọmọ Abẹokuta ni Ọlatunji Ayinde. Lẹsẹkẹsẹ ti Ayinde ta teru nipa, ni awọn alabojuto ogba ẹwọn ti ranṣẹ si awọn ọlọpa. Bi awọn ọlọpa ti de ni awọn wo gbogbo ara rẹ, ṣugbọn nwọn ko ri nkankan lara rẹ, nwọn si gbe oku rẹ lọ si Ile-iwosan lakuleku.

# APAPỌ IJỌBA FẸ KỌ ILE FUN AWỌN ỌṢIṢẸ

EKO:- Apapọ Ijọba Naijiria ti ṣe tan nisisiyi lati mu ajaga ọrun awọn oṣiṣẹ ti o ngbe inu ilu Eko ati agbegbe rẹ kuro, nwọn yio si ma a kọ ile olowo pọọku fun awọn oṣiṣẹ lati ma gbe.



Alhaji Yar' Adua

Ọrọ yi ni Alhaji Musa Yar' Adua Minista Alamojuto eto ilu Eko fun Apapọ Ijọba Naijiria sọ ninu ile Igbimọ asofin Apapọ Ijọba Naijiria ni owurọ ana ọjọ ọjọ'Ru ti ise ọjọ kọkandinlogun osu yi.

Minista na se alaye wipe, Apapọ Ijọba yio kọ ọpọlọpọ ile fun awọn oṣiṣẹ ti owo osu wọn kere.

O tun se alaye wipe, Apapọ Ijọba Naijiria ti ya sọtọ din marun ọkẹ pọun (£2,100,000) sọtọ fun eto ile kikọ awọn oṣ ṣọ na.

Alhaji na ni ni Suru-Lere ni Ijọba yio kọ awọn ile na si fun awọn oṣiṣẹ, ki Olukuluku wọn osi maa lọ wo eyiti oba wu wọn nigbati Ijọba ba pari iṣẹ awọn ile na tan.

### IYE OWO

Minista na ṣe alaye wipe, orişirişi ni awọn ile na ti Ijọba yio kọ. Awọn i'e na ko si ni ju ẹdẹgbẹta pọnun (£500) titi de ẹdẹgbẹrin (£700) lọ, ṣugbọn eyiti o ba wu oṣiṣẹ kan ni o le mu ninu rẹ.

Ijọba ti ṣe eto silẹ ti o fi jẹ wipe oṣiṣẹ kọọkan ko ni maa san ju pọnun mẹta (£3) lọ ni oṣu kan lori ile ti o ba ra. Ijọba yo si fi ye silẹ fun awọn oṣiṣẹ lati san owo ile na ni okan bi ogun ọdun.

Eyi yi fi awọn oṣiṣẹ lokan balẹ, lati ri wipe, bi nwọn ti san owo ile fun ogun ọdun, awọn na ti di onile, Ile na yio si di ti nwọn ati arọmọdọmọ wọn lẹhin wọn.

Minista na ṣe alaye pe, eto titun ti Ijọba fẹ da ọwọ le yi, yio fun ọpọlọpọ awọn oṣiṣẹ ni anfani, ekini, nwọn o di onile lẹhinti wọn ba ti san owo ile fun ogun ọdun ati ekeji awọn oṣiṣẹ yio bọ lọwọ awọn alaile — nu onile Eko ti o jẹ pe, nwọn wa ninu ajaga wọn ti ewọn ko si fẹ mọ iye ti oṣiṣẹ kan ngba ni oṣu kan, tabi iye ere ti onişowo kan nri jẹ ni oṣu kan ki n ọn to fi owo kun ile wọn lojiji ati lairo tẹlẹ.

Alhaji na fi ye gbogbo ile pe, pẹlu irọrun ni Oşişẹ kan yio maa fi san pọnun mẹta ni Oşooşu, lẹhin Ogun Ọdun ti Oşişẹ na yio si di Onilẹ.

Minista na wa ṣe alaye wipe, arundinladọfa Ọkẹ pọnun (£2, 100, 000) ni iṣẹ na yio na Apapọ Ijọba, nigbati iṣẹ awọn Ile na ba si pari, ẹdẹgbẹta (£500) ni Ijọba yio maa fi ile na silẹ fun awọn Oşişẹ.

Awọn keji ni yio jẹ ẹdẹgbẹrin pọnun (£700) mẹta na si ni nwọn o maa san titi iye owo na yio fi pe.

Onirohin wa Ejongboro fi ye wa pe, gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na lo faramọ eto na, nwọn si ti paşẹ pe ki Ijọba tete bẹrẹ iṣẹ wọn.

A lero pe ki oşu yi to pari awọn ọmọle yio bẹrẹ iṣẹ na, oniwe irohin yio lọ ya aworan adugbo na, ẹ o si ri ka ninu iwe wa nipẹyi.

## Sadauna Ko Ni Wa Si Ipade Awọn Alakoso

KADUNA :— Ni ana Ọjọ'ru ti iṣẹ Ọjọ kejidinlogun Oşu yi ni irohin kan wa ninu Ile ẹ wa, wipe Alagba Alhaji Ahmadu Bello, Olori ẹgbẹ' Ọlomi (N. P. C.) ti Alakoso Ijọba ipinlẹ Ariwa ti kọ lati wa si ipade awọn Alakoso Ijọba, eyiti nwọn fẹ ṣe laipẹ lori abayọri eto ikania.

Alagba Alhaji Ahmadu Bello sọ wipe ko si ohun ti on mọ wa ṣe ninu Ipade awọn Alakoso Ijọba nitoripe on gbọ wipe lati gba abayọri eto ikania na ni nwọn fẹ ṣe ipade le lori.

Alagba Alhaji Bello wa bere pe, Ṣe eto ti Ijọba mi ti gba, ti Apapọ Ijọba si tun ti gba ni ao ṣẹṣẹ ma a wa ṣe ipade le lori?



Alhaji Ahmadu Bello

"Ao wa ṣe ipade na pe ki Ijọba o gba a ni abi ao sọ pe Ijọba ko gbọdọ gba ohun ti nwọn ti gba ?"

Alhaji Bello ni bi nwọn ba pe ipade, on niti on, ko ni wa si ipade na ti o ba jẹ wipe lori gbigba eto ikania ni ao ṣe ipade na le lori.

O wa ṣe alaye pe, on le wa si ipade ti o ba jẹ wipe ọrọ miran ni awọn fẹ sọ tabi ti o ba jẹ wipe, awọn fẹ ṣe atunṣe lori rẹ.

Ni ipari ọrọ rẹ, Alagba Ahmadu Bello wa se alaye wipe, ninu eto ikania nibiti nwọn ti ka iwe ti awọn akọwe fi ka enia kọọkan se bi Ijọba Ipinlẹ kọọkan lo ni asoju wọn nibẹ, bi ohunkohun ko ba ye Ijọba Ipinlẹ kan, ki Ipinlẹ na obere lọwọ Asoju wọn.

Nigbati o ba si jẹ wipe, Ijọba ipinlẹ na ba ni igbẹkẹle si ẹniti nwọn o yan gẹ ni asoju ti osi mọ bi awọn eto na ti se lọ ni ẹsẹ-sẹ.

O wa pari ọrọ rẹ wipe, bi ko ba si ọrọ atata miran ti ao sọ ju gbigba abayọri eto ikania eyiti Ijọba ti gba, emi ko ni wa si ipade na o.

# IWE SI OLOTU

## Mo Ki Ọgbẹni Ọladipọ Yemitan

Olotu, Inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le gba mi laye lati le te Iwe mi yi jade lati fi ki Ọgbẹni Ọladipọ Yemitan abi gege ku bi ojo ti iṣe ẹniti o ṣe akitiyan lati le kọ Ijala ile wa jọ si ọna kanṣoṣo ti o si ṣe Iwe rẹ fun gbogbo enia lati ma a ka.

Mo mọ pe iṣẹ nla ni o jẹ fun Ọgbẹni Yemitan lati ṣe akojọ ijala na.

Mo ngbadura fun ki o le ma a ṣe iru iṣẹ na lọ si iwaju.

Ọwọ nyin yio ma roke o.

Mo dupẹ lọwọ nyin Olotu fun aye ti ẹ gba mi

Emi ni
SỌLỌMỌN ỌLADIMEJI
Ghana

## Irohin Lede Yoruba kokun To

Inu mi yio dun pupọ bi olotu ba le gba mi ni aye diẹ ninu iṣe Irohin Imọlẹ ti njade lojojumọ lati bi awọn ẹga ile-ise erọ asọrọ ma gbe tabi Redio pe nwọn ki sọ ọrọ ni ede Yoruba ni ẹkun rẹrẹ to, ati pe asiko ti nwọn nlọo titun kere ju

Irohin ni ede oyinbo amọ dada bẹna ni Irohin ni ede Hausa, irohin ni ede Ibo gbogbo tirẹ na ni on ku. ṣfi ti ede Yoruba ni ki kun rara

Asiko ti agbadun Irohin ni ede Yoruba ni yio ba pari rẹ ati pe ilu ti nwọn mọ lu ki nwọn otọ sọ ede yoruba tun ngba akoko lọtọ, oyẹ ki wọn mọ din na ku ki Irohin ni ede yoruba sile mọ gun.

Atipe irohin ede yoruba ki tun kun rara aki gbọ koko ibẹ tan ti asiko fi ro oyẹ ki e kọkọ mọ so irohin ti ilu Naijiria na ki ẹto mọ sọ ti ilu okere.

Mo dupọ lọwọ olotu fun aye ti ẹgba mi.

Emi ni
OLOYEDE
Eko

## Ilẹ Igbomi Nfẹ Atunṣe

Inu mi yio dun pupọ lati ba awọn agba lagba ilu wa sọrọ atata ninu iṣe nyin ti nkọ wa ni ọgbọn ati oye pe, ki awọn agbalagba ba awọn ọmọde fọwọ sowọpọ fun idagbasoke ilu wa, a nfẹ ki a ni nkan meremere bi awọn ilu yio ku ni Ipinlẹ Ariwa.

Ilu Ajaṣe ni ero Omi, Ajaṣe tun ni oju ọna Ọlọda, ina manaman iwa ni Ọffa ki ni ofa ti ko fi de Iu wa. bi awọn yio ku ti daro si apo Ijoba ni awa na ndawo si apo Ijọba.

Awọn ilu wọn yi nfẹ iranlọwọ Ijoba, Oke-Ọba, Oro, Ijọmu, Ese Ilu̇un, Ijan, Araodan Agbinus, Agbọnda, Omu-Aran, Edidi ati awọn miran to wa ni ile Igbomina.

A nfẹ ki awọn tan wa lọwọ bi gbogbo nkan ti nga soke ti ilaju si nposi ni o wa ni nfẹ ki awọn ilaju na mọ de ọdọ wa.

Olotu mo dupẹ fun aye ti e gba mi o.

Emi ni
J. A. OGUNGBẸSAN
Ijọmu-Ọffa.

## Ẹjẹ ki ani Ẹmi Ifẹ

Olotu ẹ dakun ẹ gba mi laye diẹ ninu iwe nyin ti njade lojojumọ lati kesi awọn ara ilu Edidi pe ki nwọn jẹ ki a ni ifẹ ara wa daada. Nitoripe irẹpọ lodun ki a ma fi ba ara wa gbe, nitorina Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba imọran mi yi.

Awọn agbalagba lo npalowe wipe alafia igi na ni alafia ẹiyẹ bẹna ni awọn baba wa tun npa lowe pe, a ki ni ọkọ nile ki a fi ọwọ ko imi (igbẹ).

Bi a ba jẹ ọmọ ilu kanna oyẹ ki a ni irẹpọ larin ara wa, bi a nfẹni kan ba wa yẹ ki gbogbo wa jọjẹ ni oyẹ wa. Ko yẹ ki a mo gbe anfani awọn elomiran sọnu.

Mo bẹ awọn ẹgbẹ ti nje "Jolly Brothers" pe ki nwọn jẹ ki arawa mọ jọ arawa loju iwa kini eleyi yio ṣe ko dara rara. Ki a fi ọwọ we ọwọ ni jẹ ki ọwọ o mọ. Irẹpọ ni yio jẹ ki a ni ilọsiwaju ni ilu wa.

Mo dupẹ lọwọ rẹ Olotu, ajinde ara wa ma jẹ o.

Emi ni,
AKỌWEDIRAN
Edidi

## Akiyesi

Ẹnikẹni ti oba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti oṣi wa laaiye tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu Itan Iṣẹdalẹ Yoruba, ki eluwarẹ kọ ọ sọwọ.

Ao si tẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ maṣe jẹki agbagbe itan Iṣẹdalẹ nitori awọn ọmọ wa.

Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU


HI ... 

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid-Ul-Kabir Dance**

AT

**FORESTER CENTENARY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn.

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, sieze this opportunity and come and listen to the latest heats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E. Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing,

**Tickets: 4/- Flat**

Tikets now on sale at 3, Oluṣhi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ Offices, Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.



**KERE O! AKIYESI PATAKI**

Awa na le jẹri wipe Ojulowo nauhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS awa na nlo n Gold Coast (Ankara Ghana)pẹlu, meji rẹ ko si ninu gbogbo oriṣiriṣi Egbogi kakiri Ilu Naijiria,




Irohin Kakiri Igboro Ilu

Bẹ na ni ẹwẹ ni igboro Ilu Eko. Irohin ti o wa lẹnu bogbo ẹ ọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn si fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn ni ipa Egbogi Iaṣa i olakiki yi ti awọn npe ni LEOPILLS o Imọran awọn Dọkita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILL yi kan sọ wipe bio ti laṣbara to ati o je Ojulowo giriki ati atamọ tase fun awọn "IẸDIJẸDI" bi o ti wu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹna ni awọn le tun fi ọwọ soya tabi ṣeleri fun gbogbo awọn ti amodi tabi Iju, tabi Igbe ṣiṣe, tabi aiko ri igbọnṣẹ dede, Iau rirun nigbakugba ara wiwo, Ẹsanri, ẹhin didun, Oju sisan, tabi aiko riran kedere kodoro buruku lara, Osiiru Onigbameji ati oriṣiriṣi arun miran gbogbo pẹlu "Wipe" awọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo Egbogi LEOPILLS nitoripe o si tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa sisọdi ọtun pọtapata

ṢE IRANT PE ALAFIA L'OGUN ỌRỌ, IJAFARA SI LEWU (POST sẹrẹ 1/9d)

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS: Igo nla ṣile mefa abọ (6/6) pere ni Igo kekere sile mẹta abọ (3/6) pere ni Bere Ojulowo Egbogi miran fun oriṣiriṣi Amọd ti o ba fẹ ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo Medcine Store
8, Palm Church Street Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Isa Faji)

# Adajọ Kotu Kan Pe Ọlọpa Ni Opurọ.

IBADAN:- Gbagada ni awọn ero ti o pejọ si ile ẹjọ kekere kan bu si ẹrin bi Adajọ kotu na Ọgbẹni Ọlayinka Odumosu ti pe ọlọpa kan ni opurọ.

Adajọ kotu na sọ pe, a se Iwọ ọlọpa yi ko ti fi irọ pipa rẹ yi silẹ, sebi o ma mi, emi na si ma ọ pe Abirọ ti tun lẹnu ni ọ.

Bi ọba pa irọ kan titi ti wọn ba fẹ lati ja ọ nse lo ntun pa omiran lati fi gbara rẹ silẹ.

Adajo Odumosun sọ ọrọ yi nigbati ọlọpa yi njẹ ri si ẹsun ole jija ti wọn fi kan ọga kan nile tẹtẹ.

Agbọ wipe awọn ọlọpa nfi ẹsun ole jija kan ọga kan ọgbẹni Albert Obikọya ati pe oti ọgbọn gba owo ti o le ni ẹgbẹrun poun (£1,250) ri ọna eru.

Ọrọ Adajọ yi waye nigbati amofin tigbẹnu fun ọdaran na ọgbẹni Ige oẹrẹ si fi ọrọ bere ọrọ lọwọ ọlọpa Tennyson Obpekpe ti se ẹlẹri Ijọba, ti osi dahun pe ohun to ranti gbogbo ohun ti wọn bere lọwọ on ma.

Sugbọn bi ọlpa yi ko ti dahun awọn ibere yi daradara, ni Adajọ bi binu ti osi sọ fun pe O tun gbe Iwa rẹ de.




AQUARIUS (Jan 20 – Feb 18) Fi gbogbo agbara rẹ ṣiṣẹ loni ki o si ṣe pẹlẹ pẹlu ọrẹ ede aiyede kan ti yio mu ọ binu loni, ti o ba si jẹ awamoto ẹsọ di ọwọ rẹ ki o maṣe pania.

PISCES (Feb 19 - March 20) Owo aṣejere atiforire wa fun ọ loni ti o ba le fi itiju rẹ silẹ ki o si ni igboiya lati ṣiṣẹ rẹ. Ọjọ si tun dara fun ọ lati lọ si irinajo.

ARIES (March 21 - April 19) ilọsiwaju yio wa fun ọ loni ti o ba le lo ọgbọn ori rẹ lati fi ṣiṣẹ maṣe gbagbe pe, nibiti alagbara gbe nṣe wahala, arọ ti o le dide njẹun.

TAURUS (April 20 - May 20) Iṣegun wa fun ọ loni lori okeiṣoro ti o wa niwaju rẹ, ṣugbọn ṣọra pẹlu inu abiju ki o ma fi ori inu ba ti ode jẹ.

GEMINI (May 21 - June 21) Ọjọ oni dara fun ọ lati ba olufẹ rẹ tage bẹni ohunkohun ti o ba dawọle rere ni yo jasi pẹlu itelọrun.

CANCER (June 22 - July 22) Olufẹ rẹ ni ifẹ rẹ lọkan ṣọra ki o ma si ṣe ma a hnwa agabagebe si, ma a mu ileri rẹ ti o ba ṣe fun ẹ ti o ba nfẹ ilọsiwaju laiye.

LEO (July 23 - Aug 22) Gbiyanju lati lo ọgbọn ori rẹ fun gbogbo ohun ti o ba fẹ ṣe loni, maṣe jẹki ẹnikẹni o ṣi ọ lọna bi bẹkọ, o da ara rẹ lẹbi ẹhin ki ilẹ to ṣu

VIRGO (Aug 23 – Sept 22) Ọjọ oni dara fun ọ, ko si okeiṣoro kan loju ọna rẹ. Ṣe iranlọwọ fun awọn ti o ba yẹ ti o si tọ fun ọ lati ṣe iranlọwọ fun

LIBRA (Sept 23 – Oct 23) Ẹnikan yo ṣe iranlọwọ fun ọ loni ayọ wa fun ọ ni ile oni, o si ṣe eto kan ti o wulo fun lẹhinna ti o ba si ba olufẹ rẹ tage, o jẹ

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Owo aṣejere wa fun ọ loni ṣugbọn ṣọra pẹlu ọrọ ẹnu rẹ ki o ma ba lugbadi ofin si ṣe pẹlẹ nitori ibinu.

SAGITTARIUS (Nov 23 – Dec 21 Ọjọ oni dara fun ọ lati lọ si irinajo ati lati ṣe ibẹwo awọn enia rẹ o si gbagbe gbogbo awọn ọrọ kan ti o ndun lọkan ti ko si mu inu rẹ dun.

CAPRICORN (Dec 22 – Jan 19) Irinajo pajawiri kan wa niwaju fun ọ loni nipa ailera kan ti o wa fun ọ ti o ba le lọ gba afẹfẹ ni ibomiran eyi le fun ọ ni alafia ati ilera.


# AKARA TU S'EPO !

## Iwe Itumọ Ala na ti de !!



Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade titi durẹ nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Ou Ifa ni awọn fi tumọ rẹ Egbogi jaburata si wfua a nin pẹlu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

J. O. SHOYINKA
N /99 Shittu Street
Ibadan



# PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara ẹgidigidi fun "Ẹpare" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigba kugba Alefọ. Egbo ẹsẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ adasin egbo, ekusẹ tabi Lapalapa, Ela, Ara sisu Akọ Ioarun ati orişirişi arun "ARA" miran gbogbo.





Gbiyanju lati dan egbogi titun ti awọn ara Ilu Tata mbulu ṣe ti won npe ni "PAYAL" wo larin ọjọ meta iwọ na yio ma rohin rẹ fun awọn ẹlomiran pelu Egbogi ipara yi ki ṣe awọn robirọbi ti wọn nta kakiri ilu ni owo poku. Ojulowo egbogi arun ara haunhaun ti ko si şişe ye meji ninu lo je eleyi si yatọ patapata si awọn ẹgẹrẹmiti adimovọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ere abgoi eko gbogbo ẹlu. Orisi meji rẹ lo wa Kekere ati nla

Bere egbogi ajẹbina Payal yi ni şọbu wọnyi:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)
(2) Adedun Chemist
Wakeman Street Yaba

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 559 THURSDAY, MARCH 19, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo k·kiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ. Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16, BAMGBOṢE STREET,

PHONE 21985, LAGOS.

# ALAKOSO IJỌBA GẸESI DE SI NAIJIRIA LANA

IKẸJA:- Gbogbo ibudo ọkọ ofurufu lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gba ero fun ogunlọgọ enia ti nwọn wa si Ebute ọkọ ofurufu Ikẹja ni alẹ ana ọjọ ọjọ'Ru ti ise ọjọ kejidinlogun ọsu yi lati wa pade Ọlọla Alec Donglas-Home Alakoso Ijọba Gẹẹsi ti ode si orilẹ-ede Naijiria lana.

Ni deede agogo mọkanla alẹ ni ọkọ ofurufu ọ l ọ l a Alec Donglas-Home de si Ikẹja.

Lesẹkẹsẹ ti ọkọ ọlọla na gunlẹ, ẹnikini ti okọkọ lọ ki Ọlọla n. ni Alhaji Abubakar Tafawa Balewa A l a k o s o apapọ Ijọba Naijiria.

Lẹhin eyi ni awọn minista Ọba, Ijoye ati awọn enia jankanjankan ti o wa pade ọlọla na wa bẹrẹsi jade ni ọkọọkan ti nwọn si nki i pẹlu ayọ.

Lẹhin ti nwọn ti ki Ọlọla na ku abọ si ilẹ wa tan ni on ati Alhaji Balewa ba ko sinu mọto ayọkẹlẹ rẹ nwọn si jijọ wọ mọto na lọ si ile Alhaji Balewa nibiti alejo na de si.

Irohin fi ye wa w i p e, Ọlọla Alec Donglas–Home yio ṣe abẹwo ọ j ọ mẹta si Orilẹ-ede Naijiria.

Oniwe irohin wa Ejongboro ti o lọ si Ikẹja ni alẹ ana fi ye wa wipe, Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria lo fi iwe ipe ranṣẹ si Ọlọla Alec Donglas Home pe, ki o wa ṣe ibẹwo Orilẹede Naijiria.

Ni kutukutu owurọ yi, Ọlọla Alec Donglas-Home yio ba Alhaji Abubakar Tafawa Balewa sọrọ ajọsọ

Ẹniti Ọlọla Alec Donglas-Home o tun ba sọrọ ayọsọ ni Dọkita Jaja Wachuku, Minista Alamojuto awọn Ilẹ Okere fun Apapọ Ijọba Naijiria.

### ỌRỌ KẸLẸKẸLẸ

Gẹgẹbi irohin ti oniwe irohin wa fun wa, ni deede agogo mejila ọsan yi, ni Dọkita Jaja Nwachuku yio mu Ọlọla Alec Dauglas-Home lọ si ọdọ Ọlọla Dọkita Nnamdi Azikwe olori Apapọ Ijọba Naijiria ninu ile rẹ, nibẹ ni nwọn o ti sọrọ kẹlẹkẹlẹ.

Lẹhinna ni Ọlọla Alec Duglas-Home yio ṣe ibẹwo ọba Alaiyeluwa Muṣẹndiku Adeniji Adele Keji.

Ti nwọn ba si ti kuro ni deede agogo kan ọsan ni Ọlọla na yio wọ mọto yika gbogbo igboro ilu Eko ati Surulere.

Bi nwọn ti nlọ si ode ni owurọ yi, oniwe irohin wa Ejongboro yio maa ba wọn lọ, ọo si gbọ gbogbo rẹ ati aworan ninu iwe wa ọla.



**Ọlọla Alec Donglas-Home**
Alakoso Ijọba Gẹẹsi


AT LAST THE WATCH WITH A PERSONAL TOUCH WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

A fortnight after receipt of your photo we will send you a Windsor watch with lifetime guarantee

Free illustrated catalogue on demand

Réf. N° 55. PHOTO



A Wonderful 15 Jewel lever shock protected movement, non magnetic, unbreakable mainspring ROLLED GOLD waterproof case and stainless steel back with your name engraved. Beautiful diamond polish raised figures, luminous and YOUR PHOTO reproduced IN COLOR on metal dial.

PRICE £ 5.

HURRY SEND YOUR PHOTO (any size) with cash or cheque

WINDSOR

19, Avenue de Lérins - Cannes, France


## Jẹki Nrọọkan Ma Jẹki Ngarun

Lati oju ewe keji

nba enia ja lẹnu iṣẹ, o nba alafia Ilu jẹ ati bẹẹbẹ lọ

Mo fi Ọlọrun bẹ nyin igba ki tọ lọ bi orere. Ẹ ma lo ipo mọ.

MO BA ISIKALUYỌ!

Awọ olorin ni ẹni mahimọ ko yọ fun ọlọmọ, nitori a mo yọ fun Anti mi Nkoyo Lolade Isikalu fun owo to gba lọwọ Ijọba Ibilẹ Eko fun ọ n a · o d i ti nwọn gba gbe mọto rẹ ni ẹmeji

Bi o ba fẹ dawọ idunnu jowọ kọwe si mi, ki nwa mu bia si ọ lọrun, nitoripe igba ponun ole mẹrin kiṣe ọmọde owo, Emi na fẹ lọ wa aloku mọto kan ra, ti awọn Ijọba Ibilẹ Eko ba gbe lọ si ọgba wọn emi na bọ si aiye niyẹn, ẹgbẹrun ọna ẹgbẹrun sini emi yio gba lọwọ wọn.

Mo si ti foju sun ilẹ kan ni Ikate ajẹpe asiko to fun emi na lati kọle, nkan ti nkọ siwaju rẹ ni pe, Ijọba Ibilẹ Eko gbe mi.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495 Phone 21985
Editor : TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S.Grammar School) Bariga Yaba Lagos 19/3/64